“Gbogbo ìjọ mi ni yoo wọ alujanna ayafi ẹni tí ó bá kọ̀

Lati ọdọ Abu Huraira- ki Ọlọhun yọnu si i- pe ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ pé: “Gbogbo ìjọ mi ni yoo wọ alujanna ayafi ẹni tí ó bá kọ̀”, wọn sọ pé: Irẹ ojiṣẹ Ọlọhun, ta ni o maa kọ̀? O sọ pe: “Ẹni ti o ba tẹle àṣẹ mi yoo wọ alujanna, ẹni tí ó bá yapa àṣẹ mi ti kọ̀”.

[O ni alaafia] [Bukhaariy gba a wa]

Anọbi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- n sọ pe gbogbo ìjọ òun ni yoo wọ alujanna ayafi ẹni tí ó bá kọ̀! Awọn saabe- ki Ọlọhun yọnu si wọn- wa sọ pé: Ta ni ẹni tí ó máa kọ̀ irẹ ojiṣẹ Ọlọhun?! O da wọn lohun pe: Ẹni ti o ba tẹle àṣẹ ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- maa wọ alujanna, ṣùgbọ́n ẹni tí o ba yapa ofin sharia ti kọ̀ lati wọ alujanna pẹ̀lú iṣẹ burúkú rẹ.

http://sunnah.global/hadeeth/yo/show/4947